*Ireti Eda…!*

**EPISODE 21**

**<u>Characters</u>**

*Abokede*
*Bello*
*Folashade*
*Mr Animashaun*
*Wosilat*
*Oyemade*

---

**Scene 1**
**Ilorin. Animashaun's residence!**

| | | |
|---|---|---|
| 1. | **SFX**: | **<u>KNOCK ON THE DOOR</u>** |
| 2. | **BELLO**: | (**CALLS OUT**) Yes? Wole! |
| 3. | **SFX**: | **<u>DOOR OPENS AND CLOSES</u>** |
| 4. | **BELLO**: | (**EXPECTANTLY**) Abokede! Bawo ni? |
| 5. | **ABOKEDE**: | (**EXCITEDLY**) Bello, guess. Jo, guess! |
| 6. | **BELLO**: | (**LAUGHS**) Mi o ti e need lati guess. Gbogbo erin oju e ti sootan |
| 7. | **ABOKEDE**: | (**EXCLAIMS HAPPILY**) Bello, Mo pass. Mo pass. Mi o believe e |
| 8. | **BELLO**: | Wow, iroyin ayo niyen o. Ma bo nibi. O deserve big hug |
| 9. | **SFX**: | **<u>KISSES</u>** |
| 10. | **ABOKEDE**: | (**IN ASTONISHMENT**) Bello, wo mi o. lehin aimoye igba ti mo tin se JAMB, mo ma ti pass i. so, emi naa ma lo university bayi? |
| 11. | **BELLO**: | Sweetheart, gbogbo nkan to da laiye yi lo to si e. emi na de dupe lowo olohun pe mo ti ni e naa, ki gbogbo awon omo university to ma sare tele e |
| 12. | **ABOKEDE**: | (**LAUGHS**) Awon iyen ke? Won o ma lenu nbe. Iwo ni ma ba dagba, darugbo. Iwo ni ma bi gbogbo omo inu mi fun. |
| 13. | **BELLO**: | (**CHUCKLES**) Gbogbo omo inu e ke? Se dozen lo fe bi ni? |
| 14. | **ABOKEDE**: | Dozen ke? Marun pere ni |
| 15. | **BELLO**: | Enh? Omo marun tan? O fe fi won tole ni? |
| 16. | **ABOKEDE**: | (**LAUGHS**) Oti gbagbe pee mi nikan niya mi bi. |
| 17. | **BELLO**: | So? Meji ti to jo |
| 18. | **ABOKEDE**: | (**PLAYFULLY**) Oda na, merin. Okunrin meji, obirin meji |
| 19. | **BELLO**: | (**AMIDST KISSES**) Oti! Meji! |
| 20. | **ABOKEDE**: | (**LAUGHING**) Oga fun e o |

21. **BELLO**: Mo mo nkan ti mo nso. Mo de mo npe iwo na fe aiye to da fun awon omo wa. (**PLAYFULLY**) Oya je ka bere nisinyi
22. **ABOKEDE**: (**CHUCKLES**) Bere kini?
23. **BELLO**: Ka bere sin sere omo naani
24. **ABOKEDE**: (**BURSTS OUT LAUGHING**) Oo serious
25. **BELLO**: (**SERIOUSLY**) Okay. A le ma bere sin bimo bayi. Sugbon, Abokede, emi ati e tin seto igbeyawo, oo de tii je kin fowo kan e rara
26. **ABOKEDE**: (**SHYLY**) Ah oti o. ko I tii ya o. ma je ka ba nkan toda bayi je o
27. **BELLO**: Ki la nbaje? Aa ba nkankan je o. sebi iyawo afesona mi ni e. ki lo fe sele?
28. **ABOKEDE**: (**EXCLAIMS**) Ah, ti nba lo loyun nko?
29. **BELLO**: (**LAUGHS**) So? Sebi mo fe fe e sile ni. Awon ebi mi ti gba e. kilotun sele?
30. **ABOKEDE**: (**SERIOUSLY**) Emi o fe fi oyun se igbeyawo o
31. **BELLO**: (**SERIOUSLY**) Okay fine! Maa lo condom.
32. **ABOKEDE**: (**SKEPTICALLY**) Condom?
33. **BELLO**: Enh. Fun eni nikan. (**KISSES**) to ba ya, aa lo ra awon ogun ifetosomobibi ko ma baa loyun titi ta ma fi setan ati ma bimo
34. **ABOKEDE**: Ogun ifeto somo bibi? Ti a ba wa se igbeyawo tan nko? Ti nba fe bimo nko?
35. **BELLO**: taba setan ati bimo, oo ko nilo ogun naa mo ni. Bii ti ose ri niyen
36. **ABOKEDE**: Se o da e loju?
37. **BELLO**: (**KISSING HER**) O da mi loju gann. Trust me!
38. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 2**

**Ilorin. Animashaun's residence.**

39. **SFX:** **<u>FOLASHADE IS CRYING. SOUND OF CRYING PERIODICALLY INTERRUPTED BY SNIFFS</u>**
40. **SFX**: **<u>DOOR OPENS AND SLAMS SHUT</u>**
41. **FOLASHADE**: (**ALARMED**) Ki ni yen? Daddy, ki lo sele?
42. **MR ANIMASHAUN**: **(ANGRILY)**Folashade! Kini gbogbo oro jati jati ti mo ngbo yi?
43. **FOLASHADE**: Daddy, kini? Mio o mo nkan ti e nso o
44. **MR A**: Iya e lo se so fun mi pe iwo ati omo (**SPITEFULLY**) Ojo yen nfe ara yin
45. **FOLASHADE**: (**SHOCKED, STAMMERS**) Dad… I …
46. **MR A**: Folashade saa roar so funmi pe iro ni won pa mo e

47. **FOLASHADE**: (**BRAZENLY**) Dad, ooto ni. Mo nife Oyemade

48. **MR A**: (**FURIOUS**) Were wa ni opolo e ni? Iwo? Folashade! O se yi tan?

49. **FOLASHADE**: Dad…

50. **MR A**: Iwo da mi. o da emi baba e. nigba ti emi nja ki ebi yi le survive, iwo nba awon esu, awon ota mi jeun

51. **FOLASHADE**: Oyemade o kin se esu daddy

52. **MR A**: Gbe enu oshi e dake Shade. Kini o mo. Awon Ojo o kin se eniyan to da rara. Lati odo baba baba won ni won ti ya esu wa

53. **FOLASHADE**: Dad, mo ti pade awon family won o daddy. Eyan dada niwon.

54. **MR A**: Eyan dada abi? Awon ti won ti pinu ati ba aiye mije ni iwon npe ni eeyan dada. Mo ri pe won ti gbe nkan fun e je

55. **FOLASHADE**: Dad, ko ri be. Mo ti meet awon family won. Won feran mi gann daddy. Ko de nse pe nitori ati ba tiyin je ni won se gbe yin lo si court.

56. **MR A**: Ah Sade. O tun ngbe seyin won. Odale omo ni iwo yi fe ya

57. **FOLASHADE**: Dad, mi o gbe seyin enikankan

58. **MR A**: Wobi, omo mi loje. Emi sini baba e. oo gbodo ri omo Ojo yen mo

59. **FOLASHADE**: Dad, emi ati e gann ti pin ya. (**TEARFULLY**) nitori tiyin naa ni mo se fi ife mi sile

60. **MR A**: O better bii tie se daaru yen. Mi o de gbodo gbo oruko yen mo ninu ile yi.

61. **FOLASHADE**: Dad, mo ma ku ni tin mi o ba fe Oyemade o. eni ti mo feran niyen o daddy.

62. **MR A**: Wobi shade, ikan lo ma fara mo. Ninu ebi e tabi omo buruku yen, waa mu kan ni o. mo de ma ko e lomo ni ti iwo ati omo yen bafi le ma tun fe ara yin

63. **FOLASHADE**: Ma de lo pokunso. Daddy, ti e o bati je kin fe eni to wunmi, nma pa ara mi ni o

64. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 3**

**Ilorin! Wosilat's house. Evening!**

65. **SFX:** **<u>DOOR OPENS AND CLOSES HURRIEDLY</u>**

66. **ABOKEDE**: Aunty Wosilat, eku ile

67. **WOSILAT**: (**GENTLY**) Kaa bo. Abokede, wo ago tolu. kini ago so?

68. **ABOKEDE**: (**APOLOGETICALLY**) Aunty ejo ema binu simi. Emi ati Bello la jade. A o mo igba ti ago lo ni ma.

69. **WOSILAT**: (**WORRIEDLY**) Abokede, ati igba ti o tin tele Bello yi jade ni o ti maa npe dele o.

70. **ABOKEDE**: Aunty mi, ema binu. Mo ma yi pada. Mi o ni ma pe nita mo

71. **WOSILAT**: (**IN A CALM BUT WARNING TONE**) Abokede, iyen ko lo ti e nba emi leru. Omo okunrin ti o ntele kiri yi, ki lo fe? Omo olowo ni. Ode mo bii ti ile tiwa seri. Ma je ko lo e nilokilo o.

72. **ABOKEDE**: (**SHYLY**) Aunty, o fe femi sile ni

73. **WOSILAT**: (**SHOCKED**) Fe e sile? Igbeyawo? Se o mo nkan ti o nso lenu bayi?

74. **ABOKEDE**: (**CHUCKLES**) Beeni aunty Wosilat. Bello ni oun fe femi sile.

75. **WOSILAT**: (**DOUBTFULLY**) Se o da e loju pe ko n sere lo nba e se bayi? Fife sile lawon omo okunrin ode oni fin tan eyin odo nisinyi o

76. **ABOKEDE**: Aunty Wosilat, ko tan mi o. oti fi mi han gbogbo awon ebi e.

77. **WOSILAT**: (**EXCLAIMS**) Abokede! oo so funmiii

78. **ABOKEDE**: Ema binu. Mo fe je ko damiloju dada kin to soro ni

79. **WOSILAT**: (**HAPPILY**, **SINGING**) Emi la o ni yo si (2x) ba a ti fe o ri, bee na lo ri, emi la o ni yo si

80. **ABOKEDE**: (**LAUGHING**) Aunty Wosilat.

81. **WOSILAT**: Abokede! Inu mi ba e dun gann ni o.

82. **ABOKEDE**: Ese aunty mi. bello ti e ti fe mu baba e wa lati wa mon eyin ati broda Ajani sugbon, daddy e ni awon nkankan ti won se ni idi se won lowo

83. **WOSILAT**: Okay. Ki won ya tete wa o. a de gbodo lo so fun baba e ni Ibadan o

84. **ABOKEDE**: koi ti ya. Ti a ba ti se tan ati lo se igbeyawo ni Ibadan, aa lo so fun baami

85. **WOSILAT**: ooto ni sha. Ko si nkan ti a kanju fun. Ko saa nse pe oti loyun?

86. **ABOKEDE**: (**SURPRISED**) Oyun ke?

87. **WOSILAT**: Kilode ti oni oyun ke? Ehin omo ode iwoyi. Abi o fe so funmi pe iwo ati Bello oti beere sini… pelu gbogbo irin ale ti e nrin

88. **ABOKEDE**: (**SHYLY**) Aunty…

89. **WOSILAT**: Wobi Abokede, emi o ni wahala o. ti o ba saa ti ma fe e sile. Sugbon ojo iwaju e ni ko saa maa wo. Ma lo loyun baaje o

90. **ABOKEDE**: beeni aunty. Emi ati Bello si so oro nipa e loni

91. **WOSILAT**: Ema kan soro nikan o. e wa nkan se si ni. Emi nisinyin ti bere sin se ifetosomobibi. IUD ni mo nlo. Mo le mu e lo si ile iwosan wa. Waa ri awon onimoniipa eto ifetosomobibi, won a si to e sona iru eyi ti ole se

92. **ABOKEDE**: Ese ma. Igba wo ni Bello ati awon ebi e le wa ri yin?

93. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 4**

**Ilorin! Oyemade's office. Morning!**

94. **SFX**: <u>**BUZZ ON THE INTERCOM**</u>

95. **VOICE**: Sir, Mr Bello Animashaun fe rii yin

96. **OYEMADE**: (**SURPRISED**) Bello Animashaun ke? Je ko wole

97. **SFX**: <u>**DOOR OPENS AND CLOSES**</u>

98. **BELLO**: Oyemade, bawo ni?

99. **OYEMADE**: Bello, kaabo si office mi. Sugbon iyalenu leyi je funmi o. se everything wa alrite? Folashade nko? Se kosi?

100. **BELLO**: Folashade o wa okay o. itori e ni mo se wa

101. **OYEMADE**: (**ALARMED**) Oh my God! Kilo se e?

102. **BELLO**: Mi o mo nkan to sele laarin eyin mejeeji sugbon Folashade ti fe se ara e lese, daddy wa gan o de gba fun

103. **OYEMADE**: Kilo se e?

104. **BELLO**: Okan e baje noni

105. **OYEMADE**: (**RUEFULLY**) Bello, Mi o mo nkan ti mo le se o. folashade funra e lo daa aarin wa ru. moni ife shade gan, ko de wunmi kaja

106. **BELLO**: Well, o gbodo wa nkan se o. o tin so npe oun ma para oun o. daddy naa de ni awon maa paa ti awon ba tun ri eyin mejeeji po

107. **OYEMADE**: (**MILDLY ANGRY**) Ki lo de ti daddy yin mu gbogbo oro yi kolekole bayi? Ija ti awon ebi wa ti nja lati odun gbogan ni daddy yin ko ti won o gbagbe yen o. awon ebi temi ti gbabgbe e, won de ti fa Folashade mora. Kilode ti daddy yin ole gba emi naa bee?

108. **BELLO**: Well, dad mi stubborn gan. Bii ti ode tun se gbe won lo si court yen gann otun dun mo won ninu. Won loose owo gan lori project ti oo je ki wo se yen. Otun je ki oju ti won

109. **OYEMADE**: Wow. So won oni je kin ever ri Shade mo niyen o?

110. **BELLO**: Well, saa wa nkan ti o fi le tuu won loju

111. **OYEMADE**: Bawo?

112. **BELLO**: Wa nkan ti ole je ki won ri gbogbo owo ti won sonu lori oro court de yen pada. Emi a pari ise lodo ti won

113. **OYEMADE**: (**THOUGHTFULLY**) Hmm. O ni business kan ti mo ni lowo bayi. Mo de mo wipe owo po nidi e gan. Se won ma like iyen ti nba gbe fun won?

114. **BELLO**: okay

115. **OYEMADE**: Sugbon mo ma need lati koko ba Kolawole, aburo mi soro naa

116. **BELLO**: Okay, baa soro. Emi a lo ba dad mi soro ki won ba le teti si e ti o ba ti wa ri won

117. **OYEMADE**: Ose gann Bello. Mo really appreciate nkan ti o nse yi

118. **BELLO**: Ko si wahala. Saa ma je kin regret e

119. **MUSIC: BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**